# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## IBẸ̀WÒ ATÒKÈWÁ (2)

## ÀDÚRÀ FÚN 22-02-2022

**AKOKO: ỌGANJỌ ORU 21-02-22 SI 12:15 OWURỌ ỌJỌ 22-02-22**

**Ìjẹ́wọ́**

Orin Dáfídì 18:1 Èmi ó fẹ̀ ọ, Olúwa, agbára mi.

Orin Dáfídì 18:2 Olúwa li àpáta mi, àti ìlú-olódi mi, àti olùgbàlà mi: Ọlọ́run mi, agbára mi, èmi ó gbẹ́kẹ̀lẹ́ e, asà mi, àti ìwo igbàlà mi, àti ilé-ìṣọ́ gíga mi.

Orin Dáfídì 18:3 Èmi ó képè Olúwa, tí ó yẹ láti ma yìn; bẹ́lì a ó sì gbà mí lọ́wọ́ àwọn ọ̀tá mi.

Orin Dáfídì 18:4 Ìrora ikú yí mi ká, àti ìṣàn-omi àwọn ènìyàn búburú dẹ́rúbà mi.

Orin Dáfídì 18:5 Ìrora ipò òkú yí mi kákìri: ikẹ̀kùn ikú dì mí mú.

Orin Dáfídì 18:6 Nínú ìṣẹ́ mi, èmi képe Olúwa, èmi sì ṣọkún pe Ọlọ́run mi: o gbóhùn mi láti inú tẹ́mpílì rẹ wá; ẹkún mi sì wá sí iwájú rẹ, àní sí etí rẹ.

Orin Dáfídì 18:7 Nígbàná ni ilẹ̀ mi, ó sì wárìrì: ipìlẹ̀ òkè pẹ̀lú ṣídì, ó sì mì, nítorítí ó bínú.

Orin Dáfídì 18:8 Èfín ti ihò imú rẹ jáde, àti iná láti ẹnu rẹ wá njónirun: ẹyìn gbiná nípasẹ̀ rẹ̀.

Orin Dáfídì 18:9 Ó tẹrí ọ̀run ba pẹ̀lú, ó sì sọ̀kalẹ̀ wá: òkùnkùn sì mbẹ lí abẹ́ ẹsẹ̀ rẹ̀.

Orin Dáfídì 18:10 Ó sì gun orí kérúbù ó sì fò: nítòtọ́, ó nrá lórí ìyẹ́-apá afẹ́fẹ́.

Orin Dáfídì 18:11 Ó fi òkùnkùn ṣe ibi ikọ̀kọ̀ rẹ: àní àgọ́ rẹ yí i ká kiri; omi dúdú, àti àwọ̀sánmà ojú-ọ̀run ṣíṣú dúdú.

Orin Dáfídì 18:12 Nípa ìmọ́lẹ̀ iwájú rẹ, àwọ̀sánmà ṣíṣú dúdú rẹ kọjá lọ, yìnyín àti ẹyìn iná.

Orin Dáfídì 18:13 Olúwa sán àrá pẹ̀lú lí ọ̀run, Ọ̀gá-ògo sì fọ ohùn rẹ: yìnyín àti ẹyìn iná.

Orin Dáfídì 18:14 Lótọ̀, ó rán ọfà rẹ̀ jáde, ó sì tú wọn ká: ọ̀pọ̀lọpọ̀ mànàmáná lí ó sì fi ṣẹ́ wọn tútú.

Orin Dáfídì 18:15 Nígbàná li àwòwò omi odò hàn, a sì rí ìpìlẹ̀ ayé nípa ìbáwí rẹ, Olúwa, nípa fífún èmí ihò imú rẹ.

Orin Dáfídì 18:16 Ó ránṣẹ́ láti òkè wá, ó mú mi, ó fà mí jáde wá láti inú omi nlá.

Orin Dáfídì 18:17 Ó gbà mí lọ́wọ́ ọ̀tá mi alágbára, àti lọ́wọ́ àwọn tí ó kórìra mi; nítorí nwọ́n lí agbára jù mí lọ.

Orin Dáfídì 18:18 Nwọ́n dojúkọ mí lí ọjọ́ ìpọ́njú mi: ṣùgbọ́n Olúwa li aláfẹ̀yìntì mì.

Orin Dáfídì 18:19 Ó mú mi jáde pẹ̀lú sínú ibi nlá; ó gbà mí nítorí inú rẹ̀ dùn sí mi.

Orin Dáfídì 18:20 Olúwa san á fún mi gẹ́gẹ́ bí òdodo mi, gẹ́gẹ́ bí mímọ́ ọwọ́ mi li ó san á fún mi.

Orin Dáfídì 18:21 Nítorí mo ti nkíyè sí ọ̀nà Olúwa, èmi kò sì fi ìkà yà kúrò lọ́dọ̀ Ọlọ́run mi.

Orin Dáfídì 18:22 Nítorí pé gbogbo ìdájọ́ rẹ̀ li ó wà níwájú mí, bẹ́lì èmi kò sì yẹ òfin rẹ̀ kúrò lọ́dọ̀ mi.

Orin Dáfídì 18:23 Èmi sì dúró ṣinṣin pẹ̀lú rẹ, èmí sí paramọ́ kúrò lára ẹ̀sẹ̀ mi.

Orin Dáfídì 18:24 Nítorínà li Olúwa ṣe san á fún mi gẹ́gẹ́ bí òdodo mi, gẹ́gẹ́ bí mímọ́ ọwọ́ mi lí ojú rẹ.

Orin Dáfídì 18:25 Fún alánu ni ìwọ ó fì ara rẹ hàn lí alánu; fún ẹnití ó dúró-ṣinṣin ni ìwọ ó fì ara rẹ hàn ní dídúró-ṣinṣin.

Orin Dáfídì 18:26 Fún ọlọ́kàn-mímọ́ ni ìwọ ó fì ara rẹ hàn ní ọlọ́kàn-mímọ́; àti fún ọlọ́kàn-wíwọ́ ní ìwọ ó fì ara rẹ hàn lí ònrorò.

Orin Dáfídì 18:27 Nítorí ìwọ ó gbà àwọn olùpọ́njú; ṣùgbọ́n ìwọ ó sọ̀ ojú ìgbéragà kalẹ̀.

Orin Dáfídì 18:28 Nítorí ìwọ ni yóò tan fìtílà mi: Olúwa Ọlọ́run mi yóò yan ìmọ́lẹ̀ sí òkùnkùn mi.

Orin Dáfídì 18:29 Nítorí pé pẹ̀lú rẹ, èmi súré la inú ogun lọ: àti pẹ̀lú Ọlọ́run mi, èmi ó fò odi kan.

Orin Dáfídì 18:30 Bí ó ṣe ti Ọlọ́run ni, ọ̀nà rẹ̀ pé: a ti rídì ọ̀rọ̀ Olúwa: òn lí àpáta fún gbogbo àwọn tí ó gbẹ́kẹ̀lé e.

Orin Dáfídì 18:31 Nítorí pé tani íṣe Ọlọ́run? tàbí tani íṣe àpáta bíkòṣe Ọlọ́run wa?

Orin Dáfídì 18:32 Ọlọ́run li ó fi agbára dì mí lí amùrè, ó sì mú ọnà mi pé.

Orin Dáfídì 18:33 Ó ṣe ẹsẹ̀ mi bí ẹsẹ̀ agbọ̀nrìn, ó sì gbé mi ka ibi gíga mi.

Orin Dáfídì 18:34 Ó kọ́ ọwọ́ mi lí ogun jíjà, tóbẹ̀ tí apá mi fa ọ̀run idẹ.

Orin Dáfídì 18:35 Ìwọ ti fi asà igbàlà rẹ fún mi pẹ̀lú: ọwọ́ ọ̀tún rẹ sì gbé mi dúró, àti ìwà-pẹ̀lẹ́ rẹ sọ mí di nlá.

Orin Dáfídì 18:36 Ìwọ sọ ìrìn ẹsẹ̀ mi di nlá nísàlẹ̀ mi, kí kókó-ẹsẹ̀ mi kí ó máṣe yẹ̀.

Orin Dáfídì 18:37 Èmi ti lé àwọn ọ̀tá mi, èmi sì bá wọn: bẹ́lì èmi kò padà sẹ́yìn títí a fi rún wọ́n.

Orin Dáfídì 18:38 Èmi ṣá wọn lí ọgbẹ́ tí wọn kò fi lè dìde, nwọ́n ṣubú lí abẹ́ ẹsẹ̀ mi.

Orin Dáfídì 18:39 Nítorítí ìwọ fi agbára dì mí lí amùrè sí ogun nà: ìwọ ti mú àwọn tí ó dìde sí mi tẹríba lí abẹ́ ẹsẹ̀ mi.

Orin Dáfídì 18:40 Ìwọ ti yí ẹ̀yìn àwọn ọ̀tá mi padà fún mi pẹ̀lú; èmi sì pa àwọn tí ó kóríra mi run.

Orin Dáfídì 18:41 Nwọ́n kígbe, ṣùgbọ́n kò sí ẹnití ó gbà wọ́n; àní sí Olúwa, ṣùgbọ́n kò dá wọn lí ohùn.

Orin Dáfídì 18:42 Nígbàná ni mo gún wọn kúnná bí ekuru níwájú afẹ́fẹ́: mo kó wọn jáde bí ohun ẹ̀gbin ní ìta.

Orin Dáfídì 18:43 Ìwọ ti yọ mí kúrò nínú ìjà àwọn ènìyàn; ìwọ fi mí jẹ olórí àwọn orílẹ̀-èdè: ènìyàn tí èmi kò tí mọ̀, yó sì ma sìn mí.

Orin Dáfídì 18:44 Bí nwọ́n ti gbúrò mí, nwọn ó gbà mí gbọ́: àwọn ọmọ ajèjì yó fi ẹ̀tàn tẹ orí wọn ba fún mi.

Orin Dáfídì 18:45: Àyà yóò pa àwọn àlejò, nwọn ó sì fi ibẹ̀rù jáde ní ibi kọ́lọ́fín wọn.

Orin Dáfídì 18:46 Olúwa mbẹ;olúkúlùkù sì li àpáta mi; kí a sì gbé Ọlọ́run igbàlà mi lékè.

Orin Dáfídì 18:47 Ọlọ́run lí ó ngbẹ̀san mi, tí ó sì nṣẹ́ àwọn ènìyàn fún mi.

Orin Dáfídì 18:48 Ó gbà mí lọ́wọ́ àwọn ọ̀tá mí, pẹ̀lúpẹ̀lú ìwọ gbé mi lékè ju àwọn tí ó dìde sí mi lọ; ìwọ ti gbà mí lọ́wọ́ ọkùnrin alágbára ni.

Orin Dáfídì 18:49 Nítorínà li èmi ṣe fi iyìn fún ọ, Olúwa, lí àwujọ àwọn orílẹ̀-èdè, èmi ó sì ma kọrin iyìn sí orúkọ rẹ.

Orin Dáfídì 18:50 Ẹnití ó fi igbàlà nlá fún Ọba rẹ̀; ó sì fí anú hàn fún Ẹni-òróró rẹ, fún Dáfídì, àti fún irú-ọmọ rẹ láíláí.

**Orin Iyìn àti Ìjọ́sìn**

**Kókó Àdúrà**

1. Afẹ́fẹ́ afẹ̀yíká Ọlọ́run, fẹ́ ifarahan àwọn ẹ̀dá ìkà dànù kúrò lójú ọ̀nà mi, ní orúkọ Jésù.
2. Ìwọ ipá ojú ọjọ́, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, fí gbogbo okun rẹ jà, kí o sì pa àwọn ọ̀tá mi ìgbà pípẹ́, tó n ṣiṣẹ́ ẹkùnrẹ́rẹ́ àti àwọn tó n ṣiṣé lábọ̀, ní orúkọ Jésù.
3. Mo fọ́ ọ̀pá ẹ̀yìn àwọn ọ̀tá mi olóríkunkun, mo sì gba àwọn ẹrù mi padà nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Ayé mi, kọ gbogbo àṣẹ ibi, ní orúkọ Jésù.
5. Ibikíbi tí wọ́n dè mí mọ́, Ẹ̀mí Mímọ́, túmisílẹ̀, ní orúkọ Jésù.

6. Àwọn agbára òkùnkùn tó n gbógun tìmí kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́, gba itìjú ìta gbangba, ní orúkọ Jésù.
7. Àhọn òkùnkùn, tó n fimí re tọ̀sán-tòru, yangbẹ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
8. Àwọn afiniṣòfò ní ọ̀sán àti ní òru, o kòní wámirí, ní orúkọ Jésù.
9. Àṣẹ sátánì lọ́gànjọ́ òru, tó fẹ́ fí ọjọ́ mi ṣòfò, ta padà báyìí, ní orúkọ Jésù.
10. Ògèdè ọgànjọ́ òru tí wọ́n ṣe lòdì sími, tí yòó farahàn lọ́sàn tàbí lóru, padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
11. Ìwọ ọjọ́ òní, gbọ́ ọ̀rọ̀ Olúwa, ìwọ yóò ṣemí ní rere láì lóṣúwọ̀n, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo ìfìmọ̀ṣọ̀kán ìkà lòdì sí ògo mi, fọ́ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo ìwé ìṣún-nkan-síwájú tí wọ́n kọ lòdì sí ifarahàn mi, jó di éérú, ní orúkọ Jésù.
14. Gbogbo olùrajà ibi, tí wọ́n ṣètò láti ra ìṣerere mi, kú nípa iná, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo ojú kẹta tó n tọpinpin ìtẹ̀sìwájú mi, gba ìfọ́jú látọ̀run wá, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo ètò àwọn oníṣẹ́ àìṣèdedé, tí wọ́n yàn láti pa mí ṣíwájú àkokò mi,ta padà, ní orúkọ Jésù.
17. Bàbá, jẹ́ kí gbogbo ohun olóríkunkun, tó n tako ìlọsíwájú èmi àti ayànmọ́ mi láyé, dẹ́kun, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo àkísà sàtánì tí wọ́n fi orúkọ, òwò, iṣẹ́, iṣẹ́-ìránṣẹ́ àti ètò-iṣúná mi gbé wọ̀, jó dì éérú, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo àmì ogun àti ìlàkàkà, tí àwọn elétò sàtánì gbé sí àgbègbè ayé mi yóòwú, ẹ̀jẹ̀ Jésù, pa wọ́n rẹ́, ní orúkọ Jésù.
20. Kòkòrò ìkùnà nínú ayé mi, ẹ̀jẹ̀ Jésù, fọ̀ jáde, ní orúkọ Jésù.
21. Mo kọ̀ láti jẹ́ ẹni tó fara gbogbẹ́ lójú ogun ayé, ní orúkọ Jésù.